# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No. 702 SATURDAY MAY 23, 1964 (2D)


## Obinrin kan Gbe Ọmọ Rẹ si Oju Titi

KANO:- Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹṣẹ ko si gba ero fun Ogunlọgọ enia ti o wa ninu ile ẹjọ nigbati awọn Ọlọpa mu awọn ọdaran meji kan, Rita Okwenyen (Ọmọbinrin) ẹni ọdun mẹdogun ati ẹgbọn rẹ Ọkunrin ti o ngbe ọdọ rẹ, Emmanuel Okwenyen, ẹni ọdun mejilelogun ti nwọn ngbe opopo Berllatt-Hughoe Kano, wa siwaju adajọ fun ẹsun pe, nwọn gbe Ọmọ ọjọ mẹwa sọnu ni ọjọ'Ru ti iṣe ogunjọ oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba awọn ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, Ọmọbinrin ni Rita, ọdọ ẹgbọn rẹ Ọkunrin ni o ngbe pẹlu, ṣugbọn ni ọjọ iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrun oṣu yi ni. Obinrin na bi Ọmọkunrin kan, nigbati o si di ọjọ kẹwa ti Obinrin na bimọ, ni on ati ẹgbọn rẹ Emmanuel ba gbe ọmọ na lọ si ibikan ti o jinna si ile wọn wọn si gbe ọmọ titun na silẹ ni oju titi.

Ṣugbọn awa ti o ri wọn nigbana pe wọn pada nigbati wọn ti rinjina di pe afira, ẹya gbe nkan nyin kia-kia sugbon wọn kọ lati gbe ọmọ na ni wọn ba fi mu wọn wa si Teṣan Ọlọpa.

Adajọ sọ pe on ko ni aṣẹ lati da ẹjọ na, o si dari ẹjọ na si ile ẹjọ giga Bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si, ẹo ma gbọ ninu iwe irohin wa.

## Ẹjọ Kotẹmilọrun Oloye Enahoro Fẹ Bẹrẹ

# OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ NRETI IDAJỌ

EKO:— Irohin kan wa gbukẹ ninu ile iṣẹ wa ni kutukutu owurọ ana ọjọ Eti ti iṣe ọ.ọ kejilelogun pe, Ijọba ti ṣetan nisisiyi lati ṣe ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Anthony Enahoro, igbakeji olori ẹgbẹ Afẹnifẹre pe, si ile ẹjọ gigajulọ fun orilẹ-ede Naijiria.

Irohin na tun fi ye wa pe, ile ẹjọ giga Eko ti bẹrẹsi fi gbogbo ara ṣiṣẹ wọn lasinmi fun iwe akọsilẹ ẹjọ na, eyi ti Ile ẹjọ gigajulọ yio lọ lori ẹjọ na.

Ninu iwe yi ni ẹṣẹ ti nwọn ka si Oloye Enahoro lẹsẹ wa ati ẹjọ ti awọn ẹlẹri Ijọba, olujẹjọ ati ẹlẹri rẹ ro niwaju Ile ẹjọ.

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn oṣiṣẹ ile ẹjọ Giga ti wọn nṣiṣẹ lori eto akọsilẹ na ko ṣe iṣẹ wọn ni gbangba, gbogbo wọn lo nṣiṣẹ kun mọri ni owurọ ana.

Oniwe irohin kan fi ye wa pe, nigbati on de inu ile iṣẹ na ni ana gbọnin-gbọnin ni awọn alaṣẹ Ile iṣẹ na ti ilẹkun ile iṣẹ wọn, ti nwọn ko si gba ẹnikẹni laye lati wọle.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹje oṣu kẹsan ọdun to kọja ni Adajọ Agba Ile ẹjọ giga Eko, Ọgbẹni Sigismund Olanrewaju Lambo, ṣe idajọ ẹwọn ọdun mẹdogun ọniṣẹ aṣẹ kara fun Oloye Anthony Enahoro nito ripe o jẹbi ẹsun idite lati doju Apapọ Ijọba bolẹ.

Ni ọjọ ru ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu kọkanla Ọdun 1962 ni Oloye Enahoro lọ si ilu Oyinbo lati Ghana ti o ngbe tele lati lọ san owo ile iwe awọn ọmọ re ki owo Ọlọpa to te Oloye na ni Londonu,

Ọlọpa na ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, Oloye Anthony Enahoro sa kuro ninu ilu rẹ nigbati Apapọ Ijọba Naijiria nba awọn enia mẹtadinlọgbọn kan ṣẹjọ pe wọn gbimọ lati gbe ogun ti Ọbabinrin Gẹẹsi ki wọn si doju Apapọ Ijọba bolẹ ki wọn si ti ipa gba Ijọba,

Nigbati wọn mu Oloye na de, ni awọn Ọlọpa ba mu lọ siwaju Adajọ Agba Ọgbẹni S. O. Lambo ni ọjọ aje ti iṣe ọjọ kerinlelogun oṣu kefa ọdun ti o koja.

Nigbati ẹjọ na bere Apapọ Ijọba ko gba, fun oloye Anthony Enahoro lati mu ogun na gbongbo Agbero Amofin Oyinbo Dingbo Foot wa si Naijiria lati wa ṣe ẹjọ oloye na nigba na.

Angbọ irohin kan ni abẹlẹpe Apapọ Ijọba yio gba fun oloye Enahoro nisisiyi ti ẹjọ na nlọ si Ile ẹjọ gigajulọ fun orilẹ-ede Naijiria lati gba Agbejọro Oyinbo ti o ba fe lati wa ba ṣe ẹjọ rẹ.

Bakanna niApapọ Ijọba gbaOloriẹgbẹ Afẹnifẹre lati gba agbejọro Oyinbo nigbati ẹjẹ wọn wa ninu ile ẹjọ giga, ṣugbọn nigbati ẹjọ na de Ile ẹjọ gigajulọ, Apapọ Ijọba gba fun Oloye Awolọwọ lati gba Agbejọro ti o ba wu u.

Lẹhin eyi ni Oloye na wa gba Agbejọro meji, Ọgbẹni Victor Durand Q. C. ati Ọgbẹni Thomas Kellock lati wa ṣe ẹjọ rẹ.

Nigbati ile ẹjọ na yio fi pari, Ile ẹjọ giga na da awọn enia mẹrin silẹ pe, ki nwọn ma a lọ layọ ati alafia.

Awọn enia mẹrin na ni Ọgbẹni J. S. Olawoyin, Ọgbẹni J. O. Lawanson, Ọgbẹni J. A. O. Akamọ ati Oloye S. T. Ọredẹhin Akọwe Agba Idasilẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Onirohin kan fi ye wa pe gbogbo awọn enia na ti adajọ ti da silẹ ni nwọn ti lọ si ilu wọn nisisiyi.

Onirohin wa kan fi ye wa pe, awọn adajọ marun ni wọn o gbo ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Enahoro pe.

Wo Oju Ewe Kẹfa



OLOYE ANTHONY ENAHORO

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU (Apa 8)

Nibiti mo ba itan mi de kẹhin niyi:—

Nigbati o sa gbogbo ipa rẹ tan, ti ko ri asọ, ti ko si ri ẹniti yio tele e, o ki ibọn rẹ, o wa sọ ninu ọkan rẹ pe "IKU YA JU ẸSIN LỌ" o ti ba ọkan rẹ pinnu lati pa ara rẹ, bi o ti ti ẹnu ibọn bọ ẹnu o gbese le oko ibọn Ojo yara tari ibọn junnu, lipa sişe bayi ẹmi rẹ ko bọ mọ.

## Lati Ọwọ J. O Shoyinka



AWORAN OKE YI NI TI AJIRAN ILU AWỌN OKU

Ige wa ranti ohun ti Ayọrunbọ sọ fun wọn lọjọ kini pe ti idamu ba de ba wọn ki nwọn pe on on yio si ran wọn lọwọ. Tita to ta si leti nigbati arakunrin rẹ sọrọ mu ki o kegbe lohun rara fun iranlọwọ lati ọdọ Ayun Ọrun-Bọ.

Nigbati iye Ogboju-le-Ogun sọ, o kepe Ayọrunbọ o ni, Ayọrunbọ o! Ẹiyẹ buburu ti njẹ lawujẹ ojẹ. Onikọ iku, ati ilẹ oku ajẹ igba enia ma wukọ.

Idamu dẹ ba wa, gba wa o, ki o to wi bayi tan. Ayun-Ọrun-bọ bẹ si arin wọn pii, oni ki lo de. Inu wọn dun tobẹ gẹẹ ti nwọn ko fi lẹ sọrọ nwọn si bu si ẹkun toripe iya ti jẹ wọn pupọ.

Ayun-Ọrun-bọ sọ fun wọn pe ki nwọn nu oju wọn nu, igbati on ba si mbẹ iya kan kole jẹ wọn, atipe ki nwọn tete sọ ẹdun ọkan wọn. toripe ẹbọra ni on, oni iye iṣẹju ti on le gba larin alaye.

Ogboju-le-Ogun ni, "Iwọ Ayun-Ọrun bọ oluranlọwọ ododo, nko ni aṣọ, nko ni owo nko si ni ẹniti yio lọ ba mi ṣe ariya ni bi igbeyawo mi toripe ni ọsan o ni Ọba yio fi Ọmọ rẹ fun mi la ti fi ṣe Iyawo.

Ọrọ na dọwọ rẹ o, Ayun-Ọrunbọ!" Ayun-Ọrun-bọ ni o tan a bi o ku? O paṣẹ fun Ogboju-le-Ogun pe ki on ati awọn ẹgbọn rẹ ma lọ si ile Ọba ti o ba ku sata ki nwọn de agbode nwọn yio ba on pade nibẹ, lo ba pora mọ wọn loju.

Nwọn de Agbode, ki nwọn to ṣẹju pẹẹ, Ayun-Ọrun-bọ yọ lọọkan pẹlu Ogunlọgọ enia, Awọn ti o ni apoti ohun alumọni ti golu, fadaka, silifa, dayamọ idi aṣọ ẹgbẹta, awọn mẹrin fa ẹṣin (horses) kọọkan dani ọkan ninu ẹsin na funfun pin ni ko ni abawọn kan rara awọn Wundia lọ rẹpẹtẹ bi ewe rumọ, ẹsẹ girigiri ko jẹki a gburo bi gangan ati Iya ilu ti ndun.

Ayọ-Ọrun-bọ ṣaju wọn irọkẹkẹ ti de ọdọ Ọba. Ayun-Ọrun-bọ bẹrẹ ati ṣ'adura fun Ogboju-le-ogun pe iyawo afẹṣe're wọle, ẹhin iyawo ko si ni mẹni iwoyi amọdun ọmọ lanti lanti ṣugbọn bi o ba dara fun ọ maṣe gbagbe awọn ẹgbọn rẹ o,

Ma si ṣe gbagbe irin ajo rẹ o tori ayaba ni eyiti o nṣe yi jẹ. Bio ti pari ọrọ rẹ odi afẹri. Ogboju-le-ogun gun ẹsin funfun, awọn ẹgbọn rẹ si gun awọn ẹṣin yoku ni ikọọkan, wọn mu ọna ile Ọba pọn.

Awọn onijo onilu arẹwa obinrin ẹru l'ọkunrin l'obinrin ti o ru apoti owo ati alumọni iyebiye tẹle wọn.

Gbogbo wọn tiri nitoripe onirunru aṣọ ni nwọn wọ.

Bi Ogboju-le-ogun ti wọ agbala Ọba pẹlu ẹmẹwa rẹ ariwo ta gee. inu Ọba ati awọn ẹbi rẹ dun pupọ wọn bẹrẹ si kan sara si Ogboju-le-ogun on paapa bẹrẹ si yọ fẹrẹ igbayi gan lo to mọ pe lai ṣe ani-ani ọmọ Ọba yio jẹ ti on.

Nitori pe igbati Ọba ti fi ọmọ re fun un tan ti nwọn si ti wa ni iyẹwu ti nwọn ugbadun ara wọn Ogboju-le-Ogun ko fẹ mọ bi nwọn jẹ, tabi nwọn mu, gẹgẹbi ẹnyin paapa ti mọ pe idẹra ya ọmọ ale ati pe awọn baba wa a ma pa lowe pe "Atitẹbi ayọ ni pa enia.

Nigbati i d ẹ r a de ba Agboju-le-Ogun tan, ko ranti nwọn ẹgbọn rẹ mọ, ebi bẹrẹ si pa wọn. Ṣugbọn mo fẹ ki ẹ mọ daju pe ki iṣe ẹjọ rẹ nitoripe ẹniti Ọba nṣe ariya fun ara rẹ ko ba mura dada ko nile jẹun nipa bibọ sibi bibọ sọhun. Eyi mu ki inu bi Vyọ-Ọrnn-bọ si Ogboju-le-Ogun.

Ayun-Ọrun - bọ wa di ẹiyẹ. Oba le tente igi ni agbala Ọba, loke bayi pe, Ogbojuleogun o! Ogbojuleogun o! Aja ki ima gbagbe olore ẹ. Emi Ayun-ọrun-bọ ẹiyẹ buburu ti njẹ larin awu jọ Ajẹ Emi oṣorongaṣ hio-



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

hio omi gbigbona ti ko ṣe bu mu,

Alagogo idẹ Arun-molo gundanu Awọn ẹgbọn rẹ wa ninu ipọnju airi jẹ, airimu iwọ nyọ ṣẹṣẹ ṣẹ, tete yara paṣẹ fun awọn ẹmẹwa rẹ ki wọn gbe onjẹ lọ fun wọn.

Bi bẹ kọ iwọ yio pada si aye rẹ. O digba kan na o oju ko fẹra ku ẹiyẹ lọ. Gẹgẹ bi mo ti sọ fun yin lakọkọ, Ogboju-le-ogun ti gbe arin awọn iwin fun ọdun jọ jọ o si ṣe akapo arọni ti iyẹn o jẹki o mọ itumọ ohun ti ẹiyẹ vi nsọ

Lọgan iye rẹ sọ, o ranti awọn ẹgbọn rẹ, nibiti nwọn gbe wa, on fun ara rẹ lọ gbe onjẹ na ru lọ fun wọn, awọn ti nwọn rọgba yika kọ ẹkọ pe, kọ si bi a ti le ni ọla, owo, ọmọ ara ohun alumọni aiye yi to, ki a gbagbe tabi ki a ma bọwọ fun aṣiwaju wa.

Nwọn jẹ onjẹ yi tifẹ-tifẹ ati tayọ-tayọ, nitori pe awọn mọ daju pe ki i ṣe ifẹ inu rẹ lati fi ebi pa wọn.

Ṣugbọn igbagbe lo ṣe e Iyawo rẹ binu gidigidi nitoripe Ogboju-le-ogun fi ori ararẹ ru onjẹ lọ fun awọn ẹgbọn rẹ, oka iru iwa bayi kun idojuti enia.

Ki Ogboju-le-ogun to bẹ rẹ si ṣe alaye fun nn. O ti bẹrẹ si sọrọ buruku fun un. Gẹgẹbi ẹnyin paapa ti mọ pe obinrin ko ni gogogo ọrọ kan ma njade lẹnu wọn ni nwọn ko mọ ko tọ rara ilu b o le b a j ẹ k o bajẹ! ni awọn obinrin si ngma a nlu nigbakugba.

O nfi ibinu ba ọkọ rẹ sọrọ bayi pe:– Ṣiọ! ṣiọ!! oṣe, o ma pọ o!!! ko si bi ati le ṣe ifa ko ma huwa ekurọ, ọmọ ti ba jẹ ọmọ ilẹ yi ilẹ, bi aba tẹni fun un ilẹ na ni yio yi si, iba ma ṣe bẹẹ ni, nwọn a pe ọ l'enia wa pe ara rẹ l'ẹranko.

Ẹru wa iwọfa wa ọmọ wa ki lo kan ọ lati fi ori ara rẹ ru onjẹ. Alailojuti enia ni ọ ki si ṣe ohun ti yu mi lẹnu.

Emi ni mo muọ wa sarin ilu wa jaiye Maa jẹ, maa mu awọ rẹ mbẹ laka. Gẹgẹ bi suru ọkunrin, ko f'esi si ọrọ rẹ ko si pinu nigbati o di ajin-dun-un o jii kalẹ o bẹrẹ si ṣe alaye ohun ti ẹiyẹ sọ fun un osi sọ iru ẹiye ti ojẹ, oni ẹiyẹ Ajẹ ni.

Atipe Ayun-Ọrun-bọ ni gbigbọ to gbọ pe ẹiyẹ ajẹ ni o fọwọ bo ọkọ rẹ lẹnu, nitoripe ọrọ ajẹ ṣoro sọ lẹnu loru. O wọlẹ ni ẹkun rẹ o si bẹrẹ si sipẹ fun ọkọ rẹ

IYOKU TUN DI ỌLA

# Ina Sọ Ogun Enia Di Alaini Ile

PORT HERCOURT; Lapẹ yi ni jamba ina nla kan ṣẹlẹ si ilu apẹja kan ni Bonny Creek ni agbegbe Port Hercort ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria. Ọpọlọpọ nkan ni ina na si bajẹ fun awọn enia ilu na.

Ọpọlọpọ awọn ohun elo awọn enia na lo jo mọ ile gẹgẹbi awọn ọkọ oju omi ni irohin fi ye wa pe nwọn ko iti mọ iye owo ti awọn nkan na yio jẹ.

Irohin fi ye wa lati ilu Port Hercourt pe awọn to lọ pa ina na ko ri nkan la ti fi ba ina na ja nitoripe awọn ọkọ oju omi yọ de ile si ti jo patapata.

## Ranṣo Ranṣo Kan Ji Obukọ O Si Wọ Ewọn Oṣu Mẹta

IJẸBU-ODE, Lẹnulọlọ yi ni ile ẹjọ kotu ganran ti Ijẹbu-Ode ju ọkunrin ranṣọranṣọ kan ti orukọ rẹ njẹ Gaduyu Raji eni ọdun marundinlọgbọn si ẹwọn oṣu mẹta fun ẹsun pe o ji Obukọ ati pe ọdaran na si sa kuro ninu itimọle ti nwọn fi si.

Agbẹjọro fun Ijọba sọ pe ni ọjọ kẹta oṣu yi ni ọdaran na ji Obukọ na ti owo rẹ jẹ pọnn kan ati sile mẹdogun lọwọ obinrin kan Iya afin Abibatu Amẹd ti i ẹpẹ

Awọn Ọlọpa si mu ọdaran na nigbati o nfẹ ta ẹran Obukọ ni ọja Ẹpẹ Ganuyu si sa kuro ninu itimọle ti nwọn fi si ati pe nwọn si tun mu.

Ọkunrin ọdaran na si gba pe on jẹbi ẹsun na ati pe o rọ adajọ na lati ṣe anu on

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 21-Feb 18) Ọrọ rẹ kan wa ni pataki ti o njẹ ayẹwo o yẹ ki o ronu wo daradara, ki o to bẹrẹ si mu ti ọrọ na ṣe nitorina mu suru maṣe bẹru, maṣe ba ẹnikan fa ijọgbọn

PISCES (Feb 19-Mar 20) Arẹ ara le ṣe ọ ki ọsan to pọn, wa aye li ọnakọna lati sun orun diẹ, iwọ yio si ji dide pẹlu igbagbọ pe aṣepọ ohun ti o dara ninu ọrọ rẹ

ARIES (Mar 21-April 20) Ijọngbọn buruku kan yio ṣẹlẹ si sakani ọdọ rẹ loni, nitorina ki o laju rẹ silẹ ni akoko owurọ yi, ki o si ṣọra ki o ma ṣe oniduro fun ẹni kẹni loni ki o ma ba dijọngbọn fun ọ

TAURUS (April 21-May 21) Bi o ba fẹ ṣe ohun kan o yẹ ki o wolẹ daradara, ki o to gbe ẹru na ru Maṣe fa o un ti ọwọ rẹ ko to ọrọ ti ko to ọrọ nj lati gba asẹko popọ lọwọ rẹ

GEMINI (May 22-June 21) Iwọ yio gbọ irohin aladun kan ni owurọ yi ki o maṣe tọrọ ohun kan bi, koṣe ki o ra tirẹ. Nṣe ni ki o fi gbogbo ọjọ oni simi ki o si sun orun diẹ

CANCER (Jun 22-July 22) Ṣe pẹlẹpẹlẹ loni nitori itu awọn enia kini ti wọ yio ba pade gbogbo nkan ti iwọ yio ba ṣe. jẹki o jẹ lori adehun ma ṣe inurẹ ti ko ni gombọ kan maṣe lo akoko danu lori ọrọ ti ko ni lari

LEO (July 23-Aug 23) Ṣe ara giri gbogbo ohun ti o jẹ ṣ ro fun ọ ni iwọ yio yanju kẹdere, tọju rẹ, maṣe agidi, ki o ma ba lọ sinu idanwo

VIRGO (Aug 24-Sept 23) Ohun ti o dara fun ọ ni pe ki idajọ rẹ jẹ otitọ laigbe sibi kan gbogbo ẹniti o ba bapade loni ni yio ma fẹran rẹ ṣugbọn ki o ṣọra ninu ohun gbogbo ti o nṣe

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Owo ni o fẹran ju, ki o si ṣọra nipa owo na maṣe jẹki ọrọ ti awọn enia nsọ yi ọ lọkan pade, gẹgẹbi isọkusọ wọn ti o ngbọ

SCORPIO (Oct 21-Nov 22) Ronu jinlẹ ki o to ma dawọ le ohun kan lati ṣe idanwo rẹ le mu ipalara dani ijọgbọn a si bẹ silẹ ṣugbọn ọgbọn ọlọgbọn ko ni jẹki o te

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Amodi kekere kan yio ṣe ọ maṣe fi ara silẹ fun amodi na, masi ṣe jẹki wahala re pọju ṣiṣẹ ni iwọntun wọnsi

CAPRICORN (Dec 22-Jan 20) Lọ ṣọra lọdọ Ọkunrin eni bajẹ kan ti o ma nsọ isọkusọ opurọ ni, gbogbo ohun t mu ọ lọju yio kuro ni ijọro ohun ti o si nfẹ yio tẹ o lọwọ loni


BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495

Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan ẹ a wo lẹẹkanṣoṣo ki o ri iyatọ*



GBOGBO RAA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣe ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa ta ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradarawọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'oyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun ọ si ded adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store

8, Palm Church Street, Lagos


## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Ayie ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu karun (24/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Ba gbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o

LATEEF BABALOLA

Akọwe Agba

# Itan Ilu Ijẹsha — Ijẹbu

Lati ọwọ ỌMỌ ABẸRU AGBA, Ijẹsha—Ijẹbu

Inu mi yio dun bi Olotu Iwe IROHIN IMỌLẸ ba le gba mi laye ninu Iwe Irohin rẹ lati sọ itan Ilu mi Ijẹbu–Ijẹsha fun gbogbo awọn ọmọ Ilu mi, paapajulọ fun gbogbo awọn onkawe wa ti nwọn ko mọ itan ilu na tẹlẹ, ki nwọn si le mọ bi nwọn ti ṣe da Ilu na silẹ ni aiye atijọ.

Ni igba kan ni Ọkunrin kan wa ti anpe ni Ayanyẹlu, Ọkunrin yi ni ọpọlọpọ Ẹru Ọkan ninu awọn Ẹru rẹ ni Ijesha. Ijesha yi ni Ayanyẹlu ọga re fẹran ju ninu gbogbo awọn ẹru rẹ yoku nitori wipe on ni ole ṣiṣẹ ju ninu gbogbo wọn. Iṣẹ ti Ayanyẹlu yi nṣe ni iṣẹ ẹmu dida, o n pẹlu awọn ẹru rẹ ni nwọn ma nda ọpẹ yi, ti nwọn ba ti de lati oko wọn agbe e ẹmu si ita awọn ara Ilu wọn ba wọn ra, ẹmu yi Nigbati opẹ awọn ara ilu yi na mọ wi nwọn ti ṣe nda ọpẹ yi, ni wọ na ba bẹrẹsi iṣe emu ti siṣe. emu wa pọ ni ilu to bẹ to fi jẹ wipe ẹmu bi Ayanyẹlu yi ko ta to bẹ mọ. o ba ni ki awọn ẹru on ma lọ ta ẹmu na ni ilu miran to wa nitosi, Iroluo-Rẹmọ, Ọkun Ọwa, Odogbolu ati Ilu miran ti owa ni to si Ayanyẹlu ati bẹbẹ lọ.

Ti awọn eru Ọgbẹni Ayanyẹlu yi ba ti fẹ lọ ta ẹmu yi ẹru rẹ ti o fẹrau rẹ yi ni o ma nse olori wọn awọn ara ilu yi ti wa mo wipe ẹmu ti o dara ni won ma ta ni ilu awon. Ti won bati bi won lere wipe tani ẹeba ra ẹmu yi won aso fun won pe Ijẹsha ni won nba ra.

Nitori idi eyi gbogbo awọn ara ilu yi fi mọ oruko Ijẹha ju ti rẹ Ayanyẹlu lọ nitori Ọga rẹ ko njade ni Ilu rẹ Odo-Ayanyẹlu yi.

Nigbati Ijẹsha yi mọ wipe wọnmọ ẹmu ti on yatọ si ti ẹlomirau ati wipe emu irẹ lo dara julọ o ba mura to gbe ẹmu rẹ lọ si Ilumira ko a mọn

Nigbati awọn ara Ilu yi mọn wipe ko gbe ẹmu wa fun awọn awọn na we mu ra ati ma lọ ba ni Ilu rẹ ti won ba ti fẹ lọ ba Ijẹsha yi ni odo– Ayanyẹlu yi ni odo ọga rẹ Ayanyẹlu, bi ọse ti ẹru rẹ Ijẹsha. Orukọ ti Ilu yi njẹ ni Odo Ayanyẹlu.

Mo dupẹ lọwọ olotu iru Aye ti ẹgba mi lati sọ diẹ nipa itan yi fun gbogbo enia. Modupe lowo yin oko Ọba ko ni sa yin lẹsẹ ogun ko ni fọhun odi yin lowo o

Bi ẹ ba si tun gba mi laye, ng'o tun sọ bi ilu na ti ṣe dagba to loni ati iru awọn oloye ti o njẹ ninu ile kọọkan laipọ pẹlu Ọba ati awọn enia jankanjankan ti nwọn ṣiṣẹ ribiribi fun idagbatake ilu wa.

Ki Ọlọrun jẹki a fi ayọ pade o

# ALA ATI ITUMỌ RE

Afara— Ti o ba nkọja lori afara, ayipada rere yio wa ninu iṣẹrẹ.

Alapata—Owo nla tabua ni riri alapata laju ala, ohunkohun ti o ba dawọle laseko na rere ni yio maa jasi.

Ago— Ti o ba ri ago ti o kun fun adiẹ tabi ẹiyẹ, ori rere lọnakọna ni itumọ rẹ.

Akara— Ti o ba njẹ, aisan. Ti o ba ri ti nwọn ndin, akowaba.

Agọ Ṣọja— Orire, Owo ati alafia ara ni itumọ rẹ.

Abẹla— Ti o ba njo, orire ni itumọ rẹ. Ti o ba ku, agbako ni eyi

Agba— Ti o ba ngbọ pe nwọn nrọ agba ni oju ala, Ṣọra ki aisan ma ba kọlu ọ.

Akapo— Ti o ba nka owo, adanu nlanla ni eyi.

Akiyesi— Fun Itumọ ala rẹ kọwe ranṣẹsi—

Joseph Alala,
c/o Posta Agent,
Itirẹ via Yaba.


# CLASSIFIED PAGE

"KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3 8 1 2, HONGKONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS".

BERE EGBOGI PATAKI YI TI NWỌN NPE NI:—

## "Figurana"

Jẹ ojulowo egbogi ti awọn Jamani ṣẹṣẹ ṣe iwadi rẹ fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba ‚TOBI' ju lati ma mu ki nwọn le fi jọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio ma a jẹ rara, bẹ sini ko lewu ni lilo fun enia rara, yala Ọkunrin tabi Obinrin.

Ki enia sanra, gborin, tabi ki o tobi pupoju, ki nṣe ohun ti o dara rara, ọpọlọpọ amodi ni onko ba enia bi Lakuregbe, Aiko le gbera nilẹ bi o ba joko, Aiya lile kiki tabi jija nigbana, Aiko le mi kan lẹ daradara Ara wiwo, tabi wiwuwo, Emi mimi họ-họ oriṣiriṣi amodi miran pẹlu.

Ṣa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ yio ri ayipada ati alafi ti yio desi. Bere ni Ṣọbu awọn Elegbogi Jamani ni igboro Ilu Eko

PILENAB MIXTURE'.

Egbogi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijẹdi tibi aiko gbọnsẹ dede ba nyọ lẹnu bere rọ ni

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




## PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mo

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhahun, atamatase egbogi fun, Ikọ here, Ikọ otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaaya, Ikọ lile. Ikọ, ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn oriṣiriṣi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Phone:- 2278 (Ọj, Lagos Nigeria
Palmchurch Street, Ita Faji)

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 702 SATURDAY, MAY 23, 1964 (2D)


## PAGIDARI IGI DA !!

IJUMU:— Ariwo nla ta, okiki si kan kakiri gbogbo ile Naijiria titi de Oke-Okun ni ojo ojo'Bo ti ise ojo kokanlelogun osu yi, pe Alufa Ijo Olorun, Oniwasu Daniel Otitoju Olubori ti Sosi ilu Ekinrin ilu kan ti ko jinna pupo si Ijumu ni agbegbe Kabba ni Ipinle Ariwa jalaisi ninu ile re lehin igbati o di eni odun marundinladorun (85years) laiye.

Lesekese ti oniwasu na jalaisi ni gbogbo awon omo Ijo re ti ranse si gbogbo Ijo ti o wa ni agbegbe na pe, "Baba wa oninure, Eniowo pa ipo da lana ao si se isinku re ni ojo Satide, ao ma a reti awon omo Ijo ati Alufa Ijo kookan.

Alufa ti ise adele fun Eniowo Ologbe na se alaye fun oniwe irohin wa pe, oninure ti emi Olorun sokale le lori ni Alufa Daniel Otitoju Olubori nigba aiye re. A ma a wo awon alaisan, a si ma a mu won lara da pelu sigbara iyanu ti Olorun fun un eyi lo si jeki Ijo re o je Ijo kan ti ko si iru re ni agbegbe na.

Ki ohun kan to sele ni Olorun yio ti fi kan ao ri ojuran ti yio si mo nkanna tele, on lo si mu isin Igbagbo denu ilu tele, on lo si mu isin igbagbo denu ilu omo Ijo Baptist ni iteleri ki o to yi pada si Apostolic.

Opolopo awon Kenferi ati aborisa lo ti yipada si igbagbo ni Ogbomosho ninu odun 1917 ti nwon ko si le gbagbe re lailai oni ni nwon o sin oku Eniowo Alufa na.

Gbogbo awon omo Ijo na ti Ologbe na ti wosan ninu aisan won ni nwon nkigbe kakiri ilu pe, "Pagidari igida, eniteere lo"

# OKUNRIN KAN NA IYA-IYAWO RE

IJEBU-ODE :- Oju gba gbogbo enia ti fun okunrin kan, Bashiru Saka, ti awon Olopa mu wa siwaju adajo Agba Ile ejo kekere Ijebu-Ode fun esun pe, o na iyawo re, o si tun na iya iyawo re pelu ni ojo ojo-'Bo ti ise ojo kokanlelogun osu yi

Olopa ti o ba Odaran na sejo se alaye fun Ile-ejo pe, Odaran na ba iyawo re ja ni ojo Eti ti ise ojo keje osu keji odun yi O si wa si Tesan awon Olopa lati wa fi esun na han Olopa.

Nigbati Odaran na rojo fun won tan, ti awon si ko oro re sile ninu iwe awon ni awon ba ranse si iyawo re pe, ki o wa ni Tesan.

Nigbati iyawo na de, on pelu iya re ni nwon jijo wa. Ki awon to bere ejo, ni obinrin na ti rojo ti o si so ohun ti o da ija sile larin awon.

Iya obinrin na ti ise iya iyawo re si so ohunti on ti nri larin awon mejeji, ati bi on ti se npari ija fun won nigbagbogbo, sugbon Odaran na ko tile jeki iya iyawo re soro tan, ti o fi gbe igbati le iya iyawo re loju gbogbo awon Olopa ni Tesan.

Olopa na tun se ala e pe bi iyawo re ti nrojo beni o nbun, ti ko si jeki awon gbo ejo ti o nro. Nigbati o fe se iya iyawo re lese ni awon ba gba sile lowo re, o tuu se alaye pe, bi ko ba si awon Olopa ti o gba Iyaafin Asimotu Bosere, sile ni ojo na, oko omo re ki ba se lese.

Nigbati iya- iyawo na, Iya afin Alimotu Bosere ro jo tan ni adajo na wa wo oke, omi ori nigba meji o si so pe kinio fe so, Saka?

Odaran na ni iro ni awon Olopa pa mo on ati iya iyawo on osi se alaye pe iya iyawo on lo lo agbada ti on wo mo on lorun bi ogun eran ti o fe pa on lojo aipe sugbon adajo ko gba oro odaran na gbo.

Ninu idajo re adajo se alaye pe ejo ti odaran na ro gba wipe o ti kuna ti o le mu iya-iyawo re binu to

Adajo na se apejuwe Sakan gegebi ogboiya okunrin ati alagbara enia kan ti ko tiki lati se ohun kohun, tobege e ti o le lo sinu iho kiniun ki o si lo ba kiniun ja ninu ile re.

Otun so siwaju ninu oro re pe, "Eru kotile ba o lati wo Tesan awon olopa lo, ti o ba ri aye re ki o si ma a lo gba awon olopa leti tabi ki o ma a lo na awon ti o ba se o"

Adajo na we pari oro re bayi pe, 'Lo ko sile I ni, gegebi o ti se na iya iyawo re, gegebe ni omo yio se na iwo na lehin na lo, eyi ki ise epe, esan ti o daju ni eyi, esan ko si gbogun"

Lehin eyi ni adajo ni ki o lo fi ponun medogun tenran si kotu, tabi ki o lo fi ewon osu meji jura

## Iyipada Ile Ise

Eyi nilati kede fun awon Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itire ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Enikeni ti o ba fe bawa ra Iwe tabi Turari Ajebidan Er o wa si ile itaja wa ni Nomba 1, Ishiba Street Odo kian Itire

## Apejuwe Ile Ise Wa

E Wo Boosi ti o nlo si Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sokale ni Lawanson, bere Ilu Itire. Ti o ba de Ilu Itire bere ibiti nwon ti npa malu, titi ibe ni itawe wa wa Ti o ba fe fi owo ranse fun oja re Adiresi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itire Via,
Suru Lere, Yaba

AWON IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egb. gi Ajebidan | 25/- |
| Iwe Ala lati owo Josefu Alala | 5/- |
| Itumo A.mi Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Sise | |
| Iwe Afose Isedale Yoruba ati psalmu Ajebidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Isegun Aje ati Adura Tete damilohun | 10/6d |
| Iwe Akomo Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/- |

## Oloye Awolowo Nreti Idajo

Lati Oju Ewe Kini

Oruko awon adajo na ni Olola Louis Mbanefo Olori gbogbo awon Adajo Agba Ipinle Ila Orun Naijiria Olola John Idemosa Lourand Taylor.

Olola Veha Bairaman Adajo Agba ilu Eko Olola Lionel Brett Adajo Agba ilu Eko ati Olola Adetokunbo Ademola Olori gbogbo awon adajo Agba fun Apapo Ijoba Naijiria

Ni ojo ti ejo na yio ba bere eo ma a gbo sugbon a gbo pe ko ni ju ose meta lo.

## Fixed Odds Special

BY POOL STAR

These are the best draws for fixed odds punters this week.

| | | |
|---|---|---|
| Budapapest | V | Bankstown |
| St Helens | v | Poloma |
| Coburg | v | Austri |
| Prahran | v | Sunshine C. |
| Polonia | v | Cumberland.. |
| Azzuri | v | Tricolore |

Printed and Published by Medupe Printing Press 16, Ilanghose Street Lagos Phone 21985
Editor:- [illegible] 45 Campbell Street, Lagos 23/5/64